# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Ketalelogun: Osu kefa Ojo karun, 2016**

**Akori Oro: Duro de Oluwa** – Apa kini

**Eko kika: Isaiah 40: 17-31**

## Afihan

Awon onigbagbo ni lati ko bi a ti nduro de Oluwa, nitoripe o se koko si igbesi aiye wa, ati-pelu o je ohun ti a nilo lati se asepe igbagbo wa ninu Oluwa. Enikeni ti o ba yan ai-duro de Oluwa yio rin irin ti won lero wipe o rorun pelu Esu; ti o si daju wipe yio yori si iparun ni ikehin.

Ni iwon igbati Olorun je oba alanu, o dara lati duro de Oluwa. Bi o tile pe loju re gegebi enia, sa duro de Oluwa nitoripe iyorisi diduro de Oluwa re yio l'ayo ati opolopo ere; nikehin aiye re yio si kun fun awon ohun ti yio mu ki o ma yin oruko Oluwa ni igba gbogbo.

## Awon ohun ti a ni lati se nigbati a ba nduro de Oluwa

Awon ohun kan wa ti o je ai-gbodo-mase, ki awon Orun le ka diduro de Oluwa wa ye ati ki o le se itewogba. Ao menuba opo ninu awon igbese yi larin eko yi.

**Igbagbo:** Enia ko le wipe on nduro de Oluwa ni alai-koko ni igbekele ninu Oluwa, O ni lati mo wipe Oluwa ni agbara lati se ohunkohun ti o muki on ma duro de. Besini o ni lati mo wipe Oluwa ko ni ja-o si olopon tabi ki o ja o kule niwon igbati o bati duro de.
O ni lati ni idaniloju wipe Olorun le yanju ijogbon/wahala ti o doju ko o, awon igbese yi ni yio tun igbagbo re se, ti yio si muki o fi suru duro de Olorun titi ti yio fi yanju gbogbo isoro aiye re. Awon onigbagbo ni lati ranti wipe "nipa igbagbo ni awa nrin, ki se nipa riri" **2 Korinti 5: 7.**
Eleyi tumo si wipe a gbagbo ninu ohun ti a ko fi oju ri sugbon ti o rorun fun Olorun lati se fun wa. A ngbe ninu aiye yi nipa igbagbo ti a ni ninu oro Olorun, ti kosi nse nipa ohun ti a fi oju ara wa ri.

Awon olufokansin nipa emi ni lati fi itara duro de Oluwa fun ireti ododo nipa igbagbo wa **Galatia 5: 5.** Nitorina, awa ti a ngbe igbesi aiye wa nipa emi ni lati fi iyara duro de Oluwa ki a le ri ohun gbogbo gba pelu awon ileri ti Olorun se fun

awon olododo ti o gbagbo ninu Re.

**Suru atiIpamora:** Ni igbakugba ti a ba ni ireti si ohun ti a ko ri, a ni lati fi suru duro de Oluwa pelu ipamora ti o ni itumo **Romu 8: 25.** Nitorina o yeki a ni ikora-eni-ni-ijanu ni igbati a ba nduro de Oluwa fun ito-ni ati ito-na. Siwajusi ki a ni idaniloju lori awon nkan ti ko ti farahan, pelu ireti wipe Oluwa yio pese won fun wa.

**Ireti:** Ti a ba nduro de Oluwa, a ni lati jeki ireti wa, wa laaye, nitori idi eyi ni bibeli se so wipe "O dara ki a ma reti ni idakeje fun igbala Oluwa" **Ekun Jeremiah 3: 26.**
Ara ninu Oluwa nigbati a ba nduro de Olorun e mase jeki a ni irobinuje okan tabi ibinuje ti o le muwa dori kodo. Sugbon e jeki a wa kun akitiyan wiwo oju-ona fun awon nkan ti o wu-wa ati awon nkan ti a nfe lati odo Olorun ki o le sele.

## Awon eko nipa diduro de Oluwa

**Duro bi ileri na ba tile lora:** Ohunkohun ti o le ma la koja lowolowo, mo feki o mo wipe ti o ba je oloto ti o si duro de Oluwa, gbogbo ileri/iran Olorun yio wasi imuse ninu aiye re. Niwon igbati o je wipe gbogbo ileri Olorun ninu Jesu Kristi ni "beni"... **2 Korinti 1: 20.**
Bi ileri na ba tile lora, ohun kan ti o gbodo mo ni wipe "ohunkohun ti o ba lora ko tumo si wipe a fi dun enia" torina duro de Oluwa.Ona Olorun ki se ona awa eda enia, torina eyikeyi ileri/iran/oro ti Oluwa ti so fun o yio pada wasi imuse bi o ba le ni suru ki o si duro de.

Ohunkohun ti Oluwa ba ranse si o nipa Iran/ala/asotele je otito ati ododo. Eleyi je ohun ti a yan fun akoko/igba kan, bi o tile lora, duro de e, nitori ni dide, yio de, ki yio pe **Habakkuku 2: 3.** Ise ti a ran si o le ma sele lesekese, sugbon lai-jafara ati dajudaju nigbati akoko ba to, ao muse laisi idaduro. Nitorina duro de Oluwa.

**Duro de eniti o le so kosese di sise**: Olorun wa je Olorun eru, torina Kristiani ni lati duro de Olorun kan soso ti o ni agbara lati jeki ojo ro, ti o si le pase fun awon orun lati seri ibukun.
Olorun kan soso ti o lagbara lati pa ara ati okan ni o yeki a duro de ju awon orisa ti won ni oju sugbon ti won ko riran, won ni imu sugbon won ko gboorun,

won ni ese sugbon won ko le rin, won ni enu sugbon won ko le soro, won ni owo sugbon won ko le lo. Olorun ti o da aiye on orun ni o ye lati duro de **Orin Dafidi 11: 3-8.**

Bere lowo ara re se awon orisa/olorun ajoji le fun o ni ojo? Tabi se ojo dede nro lati ofurufu funrare? Rara o, a fi ojo fun awa eda enia lati odo Oluwa ni. On ni Olorun alaaye ti o le se iru nkan bawon-ni, torina o yeki a duro de **Jeremiah 14: 22**.Duro de Olorun ti o lagbara lati mu ojo, yinyin, aara, oorun ati be be lo wa fun iran eda enia. On ni Oluwa ti o le pese fun aini gbogbo alaaye okan, besini On ni enikan soso ti o le ran wa lowo, torina duro de.

**Duro de Oluwa ti ki fi aye gba ibi:** O ni lati duro de Oluwa ti npa oju re mo kuro lara awon alaigboran enia, ki o si ni ireti ninu Re lati fun o ni aluyo lori awon adawole re **Isaiah 8: 17**.
Ti o ko ba le yera kuro ninu ese ati aisedede diduro de Oluwa re je lori asan, toripe oju Oluwa ki fi aye gba ibi. Bibeli jeri wipe Oluwa ma npa oju re mo kuro lara awon onise ibi, ki o maba pa won run lesekese laisi atunse **Mika 3: 4**. Olorun ko ni gbo ekun awon osika/alaigboran nigbati won ba nke fun iranlowo. Nse ni yio pa oju Re mo kuro lara won nitori gbogbo ise ibi won titi di igbati won ba ronupiwada.

**Duro de Olorun ti o le gbesan re**: Ti awon enia ba nni o l'ara, ti won ba si nse inunibini si o, duro de Oluwa lati gbesan re lara won, ki o masi se fi owo ara re gbesan tabi se idajo. Ranti ohun ti bibeli wi "olufe a mase gbesan ara yin, sugbon e fi aye sile fun ibinu; nitori a ti ko o pe, Oluwa wipe, temi ni esan, emi o gbesan" **Romu 12: 19**. Torina e mase fi oro ya oro tabi fi ibi san ibi fun enikeni, niwon igbati a ni ileri yi lati odo Oluwa.

Ti o ba feki Olorun gbesan re lara awon ota re, ki o si gba o la, duro de. Mase wipe emi o gbesan gbogbo ibi ti a se simi. Duro de Oluwa On yio si gba o lowo gbogbo awon ti nderuba o ati awon ti nmu ifoya ba o **Owe 20: 22**. Jeki Olorun sise Re ninu aiye re, mase di lowo nipa sisan esan ibi fun awon enia ti o ti huwa ibi si o.

Siwajusi, Olorun ti j'eje, kosi ni ko oro re je tabi pada sehin lori ileri Re, wipe, On yio gbesan re lara awon ota re; besini iwo yio ta'yo ni ibi gbogbo. Torina duro de **Sefaniah 3: 8**. Duro de Oluwa fun ojo ti yio fi awon ota re sun, ti yio si da ibinu gbigbona ati irunu Re le won lori.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kerinlelogun: Osu kefa Ojo kejila, 2016**

**Akori Oro: Duro de Oluwa** – Apa keji

**Eko kika: Isaiah 40: 17-31**

**<u>Awon Apejuwe Lati Inu Bibeli</u>**

Apejuwe awon enia ti won duro de Oluwa po ninu bibeli, sugbon ao menuba die lati fi idi iforo-woro yi mule. A o keko lara awon apejuwe ti ao so nipa won, wipe enikeni ti o ba duro de Oluwa ki yio kabamo sugbon yio ni ayo ainipekun.

**<u>Ebun i nu:</u>** Ileri Olorun ni wipe " awa kristiani yio je eni ibukun ju gbogbo enia lo; ki yio si ako tabi abo ninu wa ti yio yagan, tabi ninu ohunosin wa" **<u>Deuteronomi 7: 14.</u>** Olorun mu ileri yi se ninu aiye awa enia re, kosi si obinrin kan ti a daruko ninu bibeli ti o yagan bikose Mikali omobinrin Saulu **<u>2 Samueli 6: 16, 20-23.</u>**
Mikali yagan ni gbogbo igba aiye re nitoripe o kegan Dafidi eni-amioroـro Olorun ninu okan re. Iwo na mase kegan eni-amiororo Olorun tabi se ohun ti o le mu oju Olorun koro si o, ti ileri yi kofi ni wasi imuse ninu aiye re.

- **<u>Sara:</u>** Olorun fun Sara ni Isaaki ( omo ileri) lehin opolopo odun ti o ti nduro de Oluwa. Olorun yi wa laaye, yio si fun o ni omo ologo bi iwo na bale duro de **<u>Genesisi 18: 9-14.</u>**
- **<u>Rebeka:</u>** Rebeka duro de Oluwa o si ri ibeji gba, okan lara awon ibeji yi si ni Israeli awon eni-iyasoto Olorun **<u>Genesisi 25: 21.</u>** A mu agan kuro ninu aiye Rebeka, o si di iya ibeji. Iwo na duro de Oluwa ki o le gba ibeji tire loni.
- **<u>Rakeli:</u>** Eleyi duro de Oluwa, a si bukun aiye re pelu Josefu omo amu-yangan ti nse alase ile Egipti ni igba aiye re. Olorun ti o gbo adura Rakeli yio gbo adura tire na, besini odada ohun rere koni da o ni gbogbo igba aiye re.
- **<u>Aya Manoa:</u>** O duro de Oluwa, a si fun ni Samsoni omo alagbara, ti kosi akawe iru agbara re larin awa omo adari-hurun ni gbogbo agbaye (siwaju re tabi lehin re) **<u>Awon onidajo 13: 2-5</u>**. Olorun yio si'o ninu loni, besini ao fi omo ti yio je iwuri gbogbo kristiani ta o lore.
- **<u>Hanna:</u>** Hanna duro de Oluwa, o si bi Samueli okan lara awon woli nla ni ile Israeli **<u>1 Samueli 1: 19-20.</u>** Loni "Emi ni eniti nje Emi ni" yio nu omije

re nu patapata besini ibanuje ososu yio si dopin ninu aiye re.

- **Elisabeti:** Elisabeti duro de Oluwa, a si fun ni Johannu oniribomi, eniti nse atojuona-se fun Jesu Kristi Oluwa **Luku 1: 24-25, 59-66.** Jehofa ti o pa egan Elisabeti re, yio pa awon egan ti o yi o ka re nibigbogbo labe orun yi. Isele ti yio muki awon enia o ki o, ku orire, ki won si ba o yo, yio sele ninu osu yi ninu aiye re.

Gbogbo awon enia ti a menuba yi ni araiye lero wipe agan ni won, sugbon Olorun yi igbesi aiye won pada, o si fun won ni awon omo ti won ko ipa-melegbagbe larin awa eda enia.

**Iwosan:** Nigbati Hesekiah se aisan de oju iku, ko wa iranlowo awon adahunse tabi olorun-ajoji, sugbon o duro de Oluwa. Olorun wosan o si fi odun medogun kun ojo-aiye re **2 Awon oba 20: 1-6.**
Ao wo o san loni, kuro ninu awon ailera ti nfi aiye su o, besini ao fikun iye odun re ninu aiye, bi o bale duro de Oluwa.

**Ebun Emi:** Awon Aposteli ko se aigboran si ase Oluwa sugbon won duro ni Jerusalemu fun ileri Baba. Ni ojo pentekosti a fi ina se iribomi fun won **Ise awon aposteli 1: 4, 2: 1-4.**
Ti o ba sa fun ese, ti o si duro de Oluwa, Emi Mimo yio se iribomi fun o, besini iwo yio ni ore-ofe lati darapo pelu awon orun **Sekariah 3: 3-6.**

**Igbala Aiyeraye:** Simeoni duro de Oluwa lehin ti ati fihan lati odo Emi Mimo wipe koni ri iku ki o to ri Kristi Oluwa. O duro de Oluwa o si ri Itunu Israeli. O ri olugbala araiye nigbati a gbe Jesu Kristi wasi inu tempili **Luku 2: 25-32.**
Ti aba fi ohunkohun dun o, ti akoko si nlo, ti o lero wipe oti npeju; ti o ba je olotito ti o si duro de Oluwa, eleyi tumo si wipe Olorun nse awon nkankan labele ni. Oluwa nse awon ise iyanu nla ni ikoko, ti o je wipe nigbati o ba farahan gbogbo enia ni yio ba o yo , ti won yio si ki o ku ori-rere.

## Awon Ere Eiduro De Oluwa

Mo feki a mo wipe awon ere ti ao soro nipa won larin eko yi, yio farahan ninu aiye wa bi a ba le duro de Oluwa.
Niwon igbati bibeli ti jeri wipe Olorun kise enia ti yio fi seke, beni kise omo enia ti yio fi ronupiwada; amo, o le yi okan Re pada. A ma wi, ki o ma se bi? Tabi a ma soro ki o muu se? **Numeri 23: 19.**
Nitorina o yeki a gba Olorun gbo wipe gbogbo oro inu eko yi ni yio muse.

Gegebi bibeli se so wipe ohun ti o soro fun enia, o rorun fun Olorun lati se e. Nitori kosi ohun ti Olorun kole se **Luku 1: 37.**

**Ire ati oju-rere:** Duro de Oluwa ki Ole se rere ati anu fun o. Lotito Oluwa yio fi ire ati oju-rere kun aiye re, ti o ba le fi okan re saferi Re, ti o si duro de e **Ekun Jeremiah 3: 25.**
Nitorina duro de Oluwa fun oju-rere ati ire-ayo eyiti Satani nlo ategun re lati fi tan awon enia kuro ni oju-ona ododo. Jeki Olorun mo wipe On ni igbekele re, atipe nitori idi yi ni o se nfi tokantokan saferi Re.

**Olorun yio gbo ekun re, yio si re o lekun:** Ohunkohun ti o le ma sele si o, mase ya kuro ninu diduro de Oluwa, ki Oluwa ba le gbo ekun re fun iranlowo. Ni igbana ni yio yo o kuro ninu iho iparun, yio fi ese re le ori apata,yio si fi igbesi aiye re mule. Olorun yio fi orin titun si o l'enu, opo enia yio ri ayipada-otun ninu aiye re; won yio si beru, ni ona ti yio jeki won fi igbekele won sinu Oluwa titi lailai **Orin Dafidi 40: 1-3.**
Enikeni ti o ba nilo iranlowo Olorun ni lati fi suru duro de, ki O le gbo ekun won, ki osi re won lekun. Siwajusi,Olorun yio yo won kuro ninu koto ibanuje ati ewu; Yio si fi ese won le ori ile-lile, besini yio ma to isise won ninu irinajo igbagbo. Oluwa yio fi orin titun ti yio fi ogo fun Olorun sugbon ti yio dojuti awon ota won nile loko si won l'enu.
Opo enia ni yio jeri si iyalenu ti yio sele ninu aiye won nipase agbara Oluwa, ni eyiti yio si muki awon wonyi fi igbekele won sinu Oluwa lailai.

**Iwo yio jogun ile besini ao bola fun o:** Mase sako kuro ni oju ona otito nigbati o ba nduro de Oluwa, ki o ba le:

- Gbe o ga , ki o si mu o jogun ile na.
- Iwo yio ri nigbati a ba nfi iya je awon enia buburu, sugbon iwo ki yio pin ninu iya won ni Oluwa wi **Orin Dafidi 37: 34**.
- Ere re, fun diduro de Oluwa, nipe ao gbe-o-ga larin awon enia re.
- Oluwa yio fun o ni ile ti o ngbe gegebi ile-ini.
- Iwo yio ri iparun awon asebi enia ati gbogbo okan ti nhun ni o lara.

Mase se alaini-suru fun Oluwa nipa gbogbo isoro tabi wahala ti o ndojuko, Ki o bale fun o ni ile-ibi re, gegebi o ti fun awon omo Israeli ni ile Kenaani **Orin Dafidi 37:9.** Iwo yio rehin gbogbo awon enia buburu, iwo yio si je olokiki-enia besini iwo yio si jogun aiye ti o bale duro de Oluwa.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kedogbon: Osu kefa Ojo kokandinlogun, 2016**

**Akori Oro: Duro de Oluwa** – Apa keta

**Eko kika: Isaiah 40: 17-31**

## Awon ere diduro de Oluwa

Gegebi a tise ri wipe ohun ti o dara ju ki o sele si enia ni wipe ki o duro de Oluwa titi ti Olorun yio fi yanju awon isoro iru enia be. A ntesiwaju lori awon ere ti o wa ninu diduro de Oluwa.

**Oluwa yio mu o ni okan le:** Duro de Oluwa, ki o si tujuka, yio si mu o ni aiya le **Orin Dafidi 27: 14.** E jeki a ro iye owo ti awon enia nhun na lori eto-ilera ni ode-oni, amo bi o ba le duro de Oluwa, yio wo o san; besini yio fun o ni alafia pipe lofe, laigba owo lowo re.
Oluwa yio so gbogbo oke-isoro aiye re di petele, besini yio fun o ni awon ohun ti okan re npohungbe fun bi o ba le duro de e.
Siwaju si Oluwa yio fi ohun didara te o lorun, besini igba ewe re yio di otun bi ti idi ni bibeli wi **Orin Dafidi 103: 5.**
Bi o ba le duro de Olorun, ao te ojo-ori re lorun pelu awon ohun ti o dara, besini ao pa ai-ni ati iyan ohun-rere re kuro ninu aiye re. Ibukun ati Ire Oluwa yio si gba aiye re kan, ni gbogbo akoko ti iwo yio lo loke erupe.

**Enia yio ma sin o:** Ileri Olorun ni wipe, ti o ba duro de e, Oluwa yio mu o gun ibi giga aiye, iwo yio di enia pataki, ti opo-enia yio ma sin. Awon saraki enia yio si teriba niwaju re, won yio si la eruku ese re; nitoripe oju ki yio ti o; ni igba aiye re **Isaiah 49: 23.** Gbogbo okan ti o ba duro de Oluwa:

- Yio gun akaba aseyori ni agun-la.
- Won yio se aseyori debipe, won yio ma ba awon oba, awon alase ati awon olori orile-ede joko/jeun po ni awujo.
- Awon olokiki/alaisiki enia yio bola fun won, won yio sin won , besini won yio bojuto ai-ni won.

Won ki yio ni ijakule tabi idojuti nitori won farabale duro de Oluwa.

**<u>Olorun yio mu igbekele won se:</u>** Kristiani, e duro de Olorun nikan, toripe lati odo Re ni ireti yin ti nwa. E jeki o di mimo fun gbogbo enia wipe, Oluwa ni apata ati igbala yin, On ni abo yin ti ki yio jeki a si yin ni ipo **<u>Orin Dafidi 62: 5-6</u>**.
Ti o ba gba wipe ireti re wa ninu Olorun, duro de e, nitoripe yio fi anu ati idande kun aiye re ni bibeli wi **<u>Orin Dafidi 130: 7</u>**. Mo gbadura wipe anu Oluwa ti ngbeniro yio gba aiye wa kan ni akoko diduro de e, besini igbala Re yio farahan ninu aiye wa.
Niwon igbati Olorun wa je olododo, e jeki a ni ireti ai-siyemeji ni igbati a ba nduro de Oluwa **<u>Heberu 10: 23</u>**. O yeki a gba Olorun gbo wipe yio mu awon ileri Re se ninu aiye wa, nitorina e jeki a di ijewo ireti wa mu sinsin.

## <u>Ogbon ninu diduro de Oluwa</u>

**<u>Olorun nduro lati bukun o:</u>** A ni lati mo wipe <u>Olorun ko wipe ki a duro de On lasan,</u> bikosepe lati bukun wa ni. Lotito, Olorun nduro de gbogbo okan lati se ilaja pelu Re: ki won si se atunse, ki won maba pare mo aiye.
<u>Olorun nduro de wa, ki a kuro ese ati aise–dede ki o ba le fun wa ni ore-ofe ki o si fi anu gba wa.</u> Oluwa yio si gbe wa ga larin awon enia wa, bi a ba le duro de **<u>Isaiah 30: 18.</u>**
Ni iwon igbati Olorun koni inu-didun si iku enia buburu, bikosepe ki o yipada ki won si ye **<u>Esekieli 18: 23.</u>** Torina Olorun nfi ore-ofe duro de o, lati bukun o, ki o si le fi iyo'nu ati ife gba o.

**<u>Duro de Olugbala:</u>** Ojuse ni fun gbogbo kristiani lati duro de bibo Jesu Kristi Oluwa wa, eniti o gba wa lowo ibinu ti nbo **<u>1 Tessalonika 1: 10.</u>** Torina durode ipadabo olugbala araiye, eniti o gba wa lowo iberu ati idajo ti nbo lori aiye.

- Jesu Kristi gba awa olufokansin ni imoran wipe ki a mura giri ki a si duro de ipadabo Oludande wa, ti o je wipe ni igbakugba ti o ba kankun; ki a le si ilekun okan wa fun logan. Iru awon enia na ni ao bukun fun ti yio si bojuto ai-ni won ni kikun **<u>Luku 12: 36-37.</u>**
- Paulu aposteli nipa isipaya Emi mimo so wipe ki ama fi itara saferi awon ebun Emi; ki Emi mimo le tuwa-ninu ki o si se amona wani akoko ti a nduro de ifarahan Jesu Kristi Oluwa wa **<u>1 Korinti 1: 7.</u>** Nje o ni ebun Emi mimo ti o ye lati rin irinajo Igbagbo?

**E mase ilara enia enia buburu:** Duro de Oluwa lati fun o ni awon ero-ngba okan re. Ki o masi se ilara awon enia buburu ti ni ola/ngbile nipase iwa-ibi won **Orin Dafidi 37: 7.**
Ni ikorita yi, mo ni lati kilo fun awa kristiani wipe , e mase fi enikeni se afara-we ara yin; ki e maba dese niwaju Oluwa. Lotito o dara ti enia ba fi awon o dagba ju wa lo ninu Emi se awo-kose, sugbon kise ki e ma fi ara yin we enikeni. Ni igbakugba ti o ba fi ara re we elomiran ti iwo l'owo/ka'we/dagba ninu Emi ju onitohun lo, emi-igberaga yio gbe o wo. Ti o ba si je wipe eniti o juo-lo ni ilara ati owu jije yio bere, eyiti o le mu o d'ese niwaju Olorun. Nitorina duro de Oluwa fun akoko/igba tire.

**Kiyesara ki o maba subu:** Mo nse ikilo siwaju akoko na, wipe, kiyesara ki o maba subu kuro ninu idurosinsin re; ki a maba fi isina awon enia buburu fa lo kuro loju ona otito **2 Peteru 3: 17.**
Mo ti hun kio-nilo sile, torina ayanfe gbo ikilo, ki o si wa ninu isora ati igbaradi ki a maba fi asise tabi iku'na awon enia buburu fa o lo, ki o si subu kuro ninu igbagbo tabi subu kuro ni ipo re niwaju awon orun.

**A koni dojuti enia nipase wa:** Ara ninu Oluwa, o di dandan ki a funni ohun ti o ba gba, ki awon ti o nduro de Oluwa maba gba ere itiju nitori wa. Gbadura kikan wipe awon ti won gbekele Oluwa ki won ma damu nitori wa, sugbon ki aiye awon wonyi le kun fun eri-rere ti yio fi ogo fun oruko Oluwa **Orin Dafidi 69: 6.**
A ni lati gbadura, ki a gba-awe, ki a si se igbese, ki awon ti o ni igbekele ninu Oluwa; ti o si nduro de maba gba abuku nitori wa.

Lakotan, e duro sinsin, laiyese, ki e si ma po si ni ise Oluwa ni igbagbogbo; ki e si ma duro de Oluwa, pelu idaniloju wipe ise wa kise asan ninu Oluwa
**1 Korinti 15: 58.**
E jeki a je alagbara ati eniti o fesemule, ki a fi gbogbo ipa wa ati itara sise fun Oluwa; pelu igbagbo wipe gbogbo ise ti a ba se fun Oluwa ko-gbe e, toripe ao gba ere re.

**Edidi: Isaiah 40: 31**
Awon ti o ba duro de Oluwa yio tun agbara won se: won o fi iye gun oke bi idi; won o sare, ki yio si re won; won o rin, are ki yio si mu won.